# KÍKAN JESU MỌ́ AGBELEBU

## Matteu 27:27-56

## ẸKỌ 64 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ọlọrun fi ifẹ On papa si wa hàn ni eyi pe, nigbati awa jẹ ẹlẹṣẹ, Kristi kú fun wa" (Romu 5:8).**

### Èro Lọna Kalfari

A dá Jesu lẹbi ikú ori agbelebu, ikú ti o loro julọ ti o si ti eniyan loju julọ lati ọwọ awọn ọta Rẹ̀. Oun ko ṣe ohunkohun ti o yẹ si iku: ṣugbọn nitori awọn Ju n ṣe ilara si I, wọn lo ọna bayii lati mu Un kuro laaarin wọn.

Ayé ko i ti tun ri ero miiran bi eleyi ti o n wọ́ jade lati inu ilu naa lọ si Oke Kalfari. Ọmọ Ọlọrun, Ẹni ti awọn eniyan kẹgan jade lọ, "O rù agbelebu fun ara rẹ̀". Ọpọ eniyan ni o tẹle E, awọn ẹni ti o korira Rẹ̀, wọn fi ṣe ẹlẹya, wọn si lu U. Awọn kan wà ti n sọkun tẹle E paapaa awọn obinrin. Wọn sọkun nitori iwa itiju ti wọ́n hù si Oluwa wa. Nigba ti Jesu si ri wọn o sọ fun wọn pe ki wọn ma ṣe sọkun fun Oun, ṣugbọn ki wọn rò ti ipọnju nla ti o n bọ̀ wá sori awọn eniyan Israẹli nitori iwa buburu wọn yii.

Aarẹ ti mu Jesu nitori gbogbo iya ti o ti jẹ, O si ṣubu labẹ iwuwo agbelebu. Bi o ba ṣe pe iwọ wa nibẹ iwọ ko ha ni fẹ lati ba A gbe agbelebu naa? Ko si ẹni ti o jade lati ṣe iranlọwọ fun Un, nitori naa Simoni, ara ilu ibomiran, ẹni ti o n kọja lọ, ni a fi agbara mu lati gbe agbelebu naa gun ori oke. A ba le ba A ru agbelebu Rẹ̀ tayọtayọ! Nigba ti ọpọ eniyan naa de ori oke naa, a tẹ́ Jesu sori agbelebu naa a si gbá iṣo mọ́ ọwọ́ ati ẹsẹ̀ Rẹ̀. Nigba naa ni a gbe agbelebu naa soke ki gbogbo eniyan ba le ri Kristi ninu irẹsilẹ Rẹ̀. Awọn olè meji ni a kàn mọ́ agbelebu nigba kan naa lati mu Iwe Mimọ́ ṣẹ pe: "O si ṣe iboji rẹ̀ pẹlu awọn enia buburu, ati pẹlu ọlọrọ̀ ni ikú rẹ̀" (Isaiah 53:9).

### A Mú Iwe Mimọ́ Ṣẹ

O wu ni lori lati ri bi Kristi ti mu gbogbo asọtẹlẹ ti a ti sọ nipa Rẹ̀ ṣẹ perepere. A oo darukọ diẹ. Ọmọ-ẹyin kan ni o fi hàn. "Nitõtọ ọrẹ-iyọrẹ ara mi, ẹniti mo gbẹkẹle, ẹniti njẹ ninu onjẹ mi, o gbe gigisẹ rẹ̀ si mi" (Orin Dafidi 41:9). A ta A fun ọgbọ̀n owó fadaka, a si dá owo naa pada, a si lo o lati ra ilẹ isinku fun awọn talaka "Bẽni nwọn wọ̀n ọgbọ̀n owo fadakà fun iye mi. . . . . Mo si mu ọgbọ̀n owo fadakà na, mo si sọ wọn si amọkòko ni ile Oluwa" (Sekariah 11:12, 13). A na Jesu ni paṣan a si bú u: "Mo fi ẹ̀hìn mi fun awọn aluni, ati ẹ̀rẹkẹ mi fun awọn ti ntú irun: emi kò pa oju mi mọ́ kuro ninu itìju ati itutọ́ si" (Isaiah 50:6). Ko dá awọn olufisun Rẹ̀ lohun bẹẹ ni Oun ko gbiyanju lati gbeja ara Rẹ̀: "A mu u wá bi ọdọ-agutan fun pipa, ati bi agutan ti o yadi niwaju olurẹrun rẹ̀, bẽni kò yà ẹnu rẹ̀" (Isaiah 53:7). A gbá iṣo mọ́ ọwọ́ ati ẹsẹ̀ Rẹ̀: "Nwọn lu mi li ọwọ, nwọn si lu mi li ẹsẹ" (Orin Dafidi 22:16). Awọn Ju ti i ṣe eniyan Rẹ̀ ni o kan An mọ agbelebu: "Ẹnikan o si wi fun u pe, Ọgbẹ́ kini wọnyi li ọwọ rẹ? On o si dahùn pe, Wọnyi ni a ti ṣá mi ni ile awọn ọrẹ́ mi" (Sekariah 13:6). A tilẹ ti sọ tẹlẹ nipa ọti kikan ti a fun Un mu lori agbelebu "Nwọn fi orõro fun mi pẹlu li ohun jijẹ mi; ati li ongbẹ mi nwọn fun mi li ọti kikan ni mimu" (Orin Dafidi 69:21). Ọpọlọpọ iru aṣọtẹlẹ bawọnyii ni o wà bi o ba si jẹ pe awọn akọwe ati Farisi ti fẹ gba Jesu gbọ́ wọn i ba ti mọ pe Oun ni Messia naa, nitori O wi pe, "Ẹnyin nwá inu iwe-mimọ́. . . wọnyi si li awọn ti njẹri mi" (Johannu 5:39).

### Gbogbo Nnkan Daru

A kan Jesu mọ agbelebu ni agogo mẹsan-an owurọ, nigba ti o si di agogo mejila okunkun bolẹ̀. Lati agogo mejila titi di agogo mẹta ọsan okunkun naa pọ̀ gidigidi. Awọn eniyan ti wọn n kọja lọ ti wọn si ri akọle ori agbelebu naa pe, "EYI NI JESU ỌBA AWỌN JU", fi rẹrin ẹlẹya, wọn si fi ọrọ gun Un lara pe, "O gbà awọn ẹlomiran là; ara rẹ̀ ni kò le gbalà." Jesu ni agbara lati gba ara Rẹ̀ la, ṣugbọn Oun ki ba ti le mu eto irapada ṣẹ bi o ba ṣe pe Oun ti sọkalẹ lori agbelebu. Ọmọ Ọlọrun ni Jesu I ṣe, nitori bẹẹ ni Oun ṣe duro lori agbelebu lati sanwo irapada wa sọdọ Ọlọrun. Oun nikan ṣoṣo ni O le san án.

Ni agogo mẹta nigba ẹbọ aṣalẹ, iṣẹlẹ sẹ̀, awọn apata nla si fọ́. Gbogbo ẹda mi tìtì bi a ti fi Ẹlẹda rẹ̀ kọ́ si agbedemeji Ọrun ati aye, ti O si n jiya iku oro lati ọwọ awọn eniyan buburu. Nigba yii awọn eniyan wa mọ Jesu ju eniyan kan lasan, ṣugbọn o ti pẹ ju lati gbe E sọkalẹ. Oun ti mi eemi ikẹyin. Ni wakati ikẹyin ni o jẹ oró ti o pọ ju lọ.

Baba yí oju Rẹ̀ kuro nitori Oun ko le wo ẹ̀ṣẹ araye ti Ọmọ Ọlọrun rù nibẹ. Jesu kigbe pe, "Ọlọrun mi, Ọlọrun mi, ẽṣe ti iwọ fi kọ̀ mi silẹ?"

### Aṣọ Ikele Fà Ya

Loju kan naa ti Kristi ku, aṣọ ikele Tẹmpili fa ya lati oke de isalẹ. A sọ fun ni pe aṣọ ikele yii nipọn to inṣi kan, ko si le ya rara bi ko ṣe nipa agbara awamaridi ti Ọlọrun. Aṣọ ikele yii ni a ta si oju ọna ti o wọ Ibi Mimọ́ Julọ, yara ti inu ti o jẹ pe Olori Alufaa nikan ni o le wọ̀, ati eyi lẹẹkan ṣoṣo lọdun, ni ọjọ Etutu. Ẹjẹ ọdọ-agutan ti a fi rubọ fun ẹṣẹ awọn eniyan ní lati wà lara rẹ̀.

Nigba ti aṣọ ikele Tẹmpili fa ya, ọna ṣi silẹ fun olukuluku eniyan lati lọ si Ibi Mimọ́ Ju lọ, lati mu ẹbẹ wọn tọ Ọlọrun taara dipo ki alufaa maa ba wọn gbadura. Nigba ti Kristi ku O di Olori Alufaa wa, O si n lọ siwaju Ọlọrun pẹlu Ẹjẹ ti Rẹ̀ nitori ẹ̀ṣẹ wa. Nigba ti a ba n gbadura si Baba, a n gbadura ni orukọ Jesu, a si n bẹbẹ pe ki O fi Ẹjẹ Rẹ̀ ti Oun ta silẹ wẹ ọkàn wa. Nipa bayii ni a ti n ni idande, igbala kuro ninu ẹ̀ṣẹ wa nipa Ẹjẹ Jesu.

### AWỌN IBEERE

1. Nibo ni a ti kan Jesu mọ́ agbelebu? Pẹlu awọn taa ni?
2. Taa ni gbé agbelebu naa gun ori oke?
3. Ki ni o ṣẹlẹ laaarin agogo mejila ati agogo mẹta ọsan?
4. Akoko wo ni Jesu kú?  Ki ni o si ṣẹlẹ ni wakati naa gan an?
5. Bawo ni a ṣe ni lati gbadura si Baba fun igbala?